BON SECOURS HEALTH SYSTEM

**Ètò/Ìlànà**

| | | | |
|---|---|---|---|
| Akọle: | Idiyele Ati Eto Gbigba Owo | Ọjọ:<br><br>Ẹda Ti A Nlo Tẹlẹ: | 04/01//2016 |
| Isọri: | SYS.FIN | Ajọ To Fọwọsi:<br>Ajọ BSHSI | |

## ÈTÒ

O jẹ eto ile iṣẹ Bon Secours Health System, Inc. (“BSHSI”) lati maa gbe alaye jade lori eto idiyele ati owo gbigba fun awọn itọju to ṣe koko ni ile iwosan BSHSI. Eto yii, to jẹ ajọṣepọ pẹlu Eto Owo Iranwọ fun awọn Alaisan̩ (Patient Financial Assistance Policy), ni a gbe kalẹ pẹlu erongba lati tẹle àwọn àmúyẹ Abala 501(r) ti Òfin Eto Ipawo-wọle Labẹle̩ (Internal Revenue Code) ti ọdun 1986, bi won ti ṣe ayipada rẹ, nipa awọn eto owó ìrànwọ́ ati awọn eto itọju pajawiri, gbendeke lori owo ti awọn to lẹtọ lati gba iranwọ owo yoo san fun itọju, ati nini òye to kun nipa awon ọna lati díyelé ati lati gba owo.

## IBI TÍ Ó SIṢẸ́ DÉ

Ilana yi wa fun gbogbo awọ ile iwosan ile ịṣẹ BSHSI ti a ti nṣe itọju awọn aisan to le ati itọju pajawiri. Eyikeyi ile iṣẹ to nba BSHSI gba owo yoo tẹle , yoo si ṣe atilẹyin fun awọn akojọpo eto BSHSI lori owo gbigba to wa nisalẹ yi. Ayafi ti a ba yi ipinnu yi pada, eto yi ko si fun awọn oníṣègùn tabi awọn onișe iṣegun miran, o kan awọn wọnyi , sugbọn ko mọ ni awọn wọnyi: o kan awọn oníṣègùn iyara pajawiri (emergency room physicians), dokita to nkun awọn ti wọn nṣe iṣẹ abẹ fun loorun (anesthesiologists), awọn dokita to nlo awọn irin iṣẹ imọ ẹrọ lati mọ ati lati wo aisan to nṣe ni (radiologists), awọn dokita to fi ile iwosan ṣe ibujoko (hospitalists) ati awọn dokita ti iṣẹ wọn da leri siṣe ayẹwọ awọn kokoro to nda agọ ara laamu (pathologist).

## IDI FUN ETO YI

Eto yi waye ki o ba lee ṣeeṣe fun ile iṣẹ BSHSI lati fi ìdíyelé to ṣe deede, to wa lasiko, to si ba awọn ofin ati ilana mu fun awọn oniduro tabi ẹlomiran to fẹ ba alaisan san owo itoju.

BSHSI ati awọn ile iṣe Abanigbowo yoo ri pe awọn eto ti wọn gbe kalẹ tẹle ofin ijọba apapọ, ijọba ipinlẹ ati ijọba ibilẹ, ati awọn ilana ati ofin to nsakoso awọn ilana bii, Ofin To Wa Fun Sisin Gbese Lọna To Tọ (Fair Debt Collection Practices Act , FDCPA). Ninu adehun wọn pẹlu BSHSI, ọkọọkan awọn ile iṣe Abanigbowo yoo gba lati maa ṣe itọju gbogbo awọn alaisan, awọn oṣiṣẹ ati awọn alabaṣiṣepọ pẹlu Akọmona Ati Aṣa Bon Secours Health System. Siwaju sii,

ọkọọkan awọn Abanigbowo yoo ṣeleri pe oun yoo ṣe iṣe oun gẹgẹ bi asa awọn ile ise to nṣe iru iṣẹ bẹẹ.

**AWỌN ITUMỌ**

Iye Owo Ti O Wa Fun Sisan Fun Eyikeyi Itọju (Amounts Generally Billed (AGB) – Iye owo ti o wa fun sisan fun eyikeyi itọju tumọ si owo ti a maa nsaba nbere lọwọ alaisan fun itọju pajawiri ati eto ilera fun awọn to ni eto adojutofo (insurance) fun iru awọn itọju bẹẹ. Iye owo ti wọn nfun awọn to lẹtọ si owó ìrànwọ́ ko gbọdọ ju Iye owo ti o wa fun sisan fun eyikeyi itọju ("AGB") lọ. Awọn iye owo yi da lori, iye ti awọn to ni eto ilera medicare ati awọn to maa nsan owo fun iwosan lẹtọ lati san fun iwosan pajawiri ati awọn eto ilera miran to se pataki. Iye ti a le gba jẹ iye ti ile iṣẹ adojutofo yoo san, ati ti o ba wa, owo ti ẹni naa yoo san funra rẹ. A le mọ AGB nipa lilo ọ̀nà 'wiwo ẹyin wo gẹ̀gẹ̀ bí abala 26 ti CFR, ẹsẹ 1.50'( look back method per 26 CFR §1.501(r)), eleyi ti ayipada le ba ni igba de igba. Wo APPENDIX A fun àfikún alaye siwaju sii nipa eto ẹdinwo AGB .

Gbese Ti Ko See Gba Pada – Gbese to wa ni akanti oniduro kan, ti ó di fifagile pe ko ṣee gba pada mọ

Abanigbowo-"Abanigbowo" ni ile iṣẹ ti ile iwosan kan bẹ lọwẹ lati ba wọn sin awọn oniduro lowo tabi lati gba owo lọwọ awọn oniduro.

Asiko Ti Anfani Wa – Asiko ti ọniduro le ri owó ìrànwọ́ gbà.

Gbigba Owo ni Ọna Àrà-Ọ̀tọ̀ (Extraordinary Collection Action ,ECA) - Gbigba Owo ni Ọna Àrà-Ọ̀tọ̀ (ECA),gẹgẹbi awọn ofin IRS, le jẹ ọkan ninu awọn wọnyii:

- Tita gbese ẹnikan fun ẹlomiran
- Fifi iroyin buburu nipa onigbese ranṣẹ si awọn ile iṣẹ to ngba iroyin nipa gbese tabi si awọn ile iṣẹ to nṣe akọsilẹ gbese.
- Sisun itọju siwaju, kikọ̀ lati se itọju tabi bibere fun owo ki wọn to ṣe ìtọ́jú awọn ti ko tii sanwo itọju ti wọn gba tẹlẹ.
- Awọn igbeṣẹ to nilo fifi ẹsẹ ofin tọ wa ninu awon wọnyi, sugbọn ko pin si awọn wọnyi.
    - Gbigbẹsẹ le dukia
    - Gbigba ilẹ ti wọn fi yawo pada lọwọ ẹni to jẹ gbese
    - Gbigbẹsẹ le akanti ile ifowopamọ tabi awọn dukia onigbese miran
    - Gbigbe onigbese lọ si ile ẹjọ fun esun ti kiise ti ọdaran
    - Síṣe okunfa fifi agbofinro mu eni naa.
    - Mimu eniyan ati dukia rẹ lọ si ile ẹjọ ni tipatipa.
    - Gbigbẹsẹ le owo osu oniduro

Kikọwe pe eniyan to ba wọ gbese ko lẹtọ lati jẹ anfani eto gbigba owo ni ọna to le.

Oniduro – Alaisan, Olutọju, tabi ile iṣẹ to ni lati san owo itọju fun iwosan.

Eto Owó Iranwọ Fun Awọn Alaisan - Eto yi wa fun dídin gbese ti oniduro jẹ ku. Eto yi wa fun awọn oniduro ti wọn ko ni eto adojutofo tabi ti eto adojutofo wọn ko muna doko to si jẹ pe ti wọn ba san owo ti wọn jẹ ni kíkun tabi ti wọn ba san ninu owo ti won jẹ yoo mu inilara ailowolọwo ba wọn.

Ojuṣe Alaisan Fun Alaisan To Ni Eto Adojutofo - "Ojuṣe Alaisan" jẹ iye owo ti alaisan ni lati san fun ra rẹ lẹyin igba ti ile iṣe adojutofo bati sọ iye owo to yẹ ki wọn san fun.

Ojuṣe Alaisan Fun Awọn Alaisan Ti Ko Ni Eto Adojutofo - Iye owo to yẹ ki alaisan san lẹyin igba ti o ba ti lo AGB ti agbegbe rẹ.

- ECA Ti Wọn Fi Aye Gba. – Botilẹjẹpe oriṣiriṣi eto gbigba owo ni ọna to le lo wa ti wọn npe ni ECA. ECA kan soso ti BSHSI yoo lo ni fifi ejọ onigbse sun awọn ile iṣẹ to ngba iroyin nipa gbese tabi si awọn ile iṣẹ to nṣe akọsilẹ gbese, gẹgẹ bi o ti yẹ.

Alàgàta To Nsan Owo - Ile iṣẹ, ti kii se alaisan (ẹni kinni) tabi awọn ile ịṣẹ eto ilera (ẹni keji) ti wọn nsan owo awọn eto ilera ara ẹni

Awọn Eniyan Ti Eto Adojutofo Wọn Ko Kun Oju Osuwọn To (Underinsured) - Ẹni to ni eto adojutofo sugbọn ti wọn gba idiyele fun awọn itoju ti ko si lara itoju ti eto adojutofo rẹ kapa. Awọn apẹẹrẹ naa ni wọnyi, sugbọn ko mọ ni awọn wọnyi: Awọn oogun Medicare to wa fun ṣiṣe itọju ara ẹni, lilo awọn anfani ti eeyan ni labẹ eto ilera tan patapata, yiyọ awọn itọju kan kuro ninu ẹ̀tọ igbẹbi, ati bẹẹbẹẹ lọ.

Eni Ti Ko Ni Eto Adojutofo – Awọn alaisan ti ko ni eto adojutofo

## ILANA

Atojọ Awọn Ikọsilẹ Owo Sisan Ati Idiyele
Awọn oniduro le beere akọsilẹ owo ti wọn san ati idiyele ni igbakugba lai san owo rara.

Awọn Ede-aiyede
Eyikeyi oniduro lee tako akọsilẹ kankan ninu idiyele wọn . Awọn oniduro lee bẹrẹ ede-aiyede nipa kikọ iwe tabi lorị ẹrọ ibanisọrọ pẹlu awọn asoju eto itọju oníbàárà.Ti awọn oniduro ba bere iwe to wa nipa idiyele wọn, awọn oṣiṣe ile iṣe yoo lo gbogbo agbara wọn lati rii pe wọn fun oniduro ni iwe naa laarin ọjọ iṣẹ mẹta .

Sáà Ìdíyelé
Sáà Idiyele (Billing Cycle) ti ile iṣẹ BSHSI bẹẹrẹ lati ọjọ akọkọ ti akọsilẹ waye ti yoo si pari lẹyin ọgọfa ọjọ to bẹrẹ. Laarin sáà idiyele, awọn oniduro le gba awọn ipe, atojọ awọn akọsilẹ ati awọn lẹta lati ọdọ wa. Awọn ipe le wọle fun oniduro ni gbogbo sáà idiyele. Ni isale yin i awọn igba ti a fi lelẹ fun gbigba awọn idiyele ati awọn lẹta:

- A o fi Atojọ awọn akọsilẹ gbese ransẹ si oniduro nigbati o ba dipe a rii pe oniduro njẹ owo.
- Leyin ọgbọn ọjọ ti oniduro ti gbọ pẹ owo rẹ ti to san, oniduro yoo gba lẹta miran
- Lẹta keji yoo di fifi ranṣe lẹyin ọgbọn ọjọ ti lẹta akọko ti o sọ fun oniduro pe akanti gbese rẹ ko tọna mọ.
- A o fi lẹta kẹta to jẹ eyi to gbẹyin ranṣe lẹyin ọgbọn ọjọ ti lẹta keji ti sọ fun oniduro pe akanti gbeṣe rẹ ko tọna mọ ati pe akanti naa yoo di gbigbe fun awọn ile iṣẹ Abanigbowo.
- Ni ọjọ ọgọfa sáà idiyele, a o fi akanti oniduro sọwọ si ile iṣe abani-gbowo .Ile iṣẹ abani-gbowo yoo jẹ ko di mimọ fun alaisan nipasẹ iwe atojọpọ eto idiyele ni ogbọn ọjọ ko to dipe wọn yoo gbe eyikeyi ninu awọn igbẹsẹ gbigba-owo-ni-ọna-to-le ti wọn fẹ lo. Iwe naa yoo si sọ gbedeke ti wọn fun-un, lẹyin eleyi wọn yoo gbe igbẹsẹ lori eyikeyi ECA

tabi awọn ECA, eleyi ti yoo si sọ nipa ona abayo lati gba iranwọ l'erefe ni ede to rọrun lati mọ.

Ọkọọkan gbolohun ati lẹta ti a nlo ninu Sáà Idiyele wa ni awọn atotonu nipa ọna ati san owo, asayan owo sisan, ikanni ayelujara to nṣe iranwọ owo ati nọmba ẹrọ ibanişọrọ eto itọjụ onibàárà.

## ÈTÓ ÀWỌN ÌLÀNÀ

Wo Afikun B (Appendix B) Fun Eto Awọn Ilana.

<u>AFIKUN A</u>

<u>AGB</u>

Fun alaye kikun nipa eto ẹdinwo AGB, e lọ sí ori ikanni ayelujara: www.fa.bonsecours.com tabi nipa pipe ẹ̀ka itọju onibara ni (Lábẹ́lé) 804-342-1500 tabi (Laisan owo) 1-877-342-1500. Fun ẹ̀ka itọju onibara to wa ni Ile Iwosan Gbogbonìṣe Rappahannock, jọwọ pe 804-435-8529.

## AFIKUN B

## ETO AWỌN ILANA

Eyi ni awọn ilana ti a gbe kalẹ fun iranlọwọ awọn oṣiṣe lati jẹ ki ala eto yi di mimu ṣẹ. Nigba ti o ba ntẹle awọn agbekalẹ awọn eto wọnyi, awọn osiṣẹ ni lati lo ọgbọn ori wọn ninu iṣe ti woṅ nṣe ati/tabi awọn ojuṣe iṣẹ wọn.

### Eto Idiyele Fun Awọn Ti Ko ni Oniduro

1. Gbigba Atotonu Lori Eto Adojutofo To Wa: BSHSI yoo gbiyanju to dara lati gba atotonu lọwọ alaisan boya o ni eto adojutofo aladani tabi ti ijọba to le san lara tabi san gbogbo owo itọju ti ile iwosan ṣe fun alaisan.

2. Fifun Alàgàta Ni Iwe Idiyele: Ile iwosan yoo fi taratara sin owo ti ẹnikẹta jẹ awọn naa ni, sugbọn ko pin si: awon onișẹ abanisanwo ti won gbeṣẹ fun ati awọn onișẹ abanisanwo ti wọn ko gbesẹ fun, awọn to nduro fun ni, awon to nfi ọkan ẹni balẹ lori gbese (indemnity payers) ati awọn ile iṣe to nseto adojutofo fun awọn ọkọ, ati awọn to nsanwo fun eto ijọba ti wọn ni ojuṣe lati maa san owo itọju alaisan. Laifi akoko sofo, BSHSI yoo fi idiyele sọwọ si gbogbo awọn alàgàta tọrọ kan nipasẹ atotonu ti awọn alaisan tabi asoju wọn fi silẹ tabi fọwọsi .

### Idiyele Fun Oniduro

Atojọ awọn akọsilẹ ati orișirișị lẹta ni a nlo lati sọ fun awọn oniduro ipo ti akanti wọn wa. Okọọkan atọjọ awọn akọsilẹ ati lẹta ni awọn wọnyi: atotonu lori awọn ọna ti won lee fi san owo, iranwọ owo ati nọmba ti wọn le pe fun awọn ibeere.

1. Dídíyelé Awọn Alaisan Ti Wọn Ni Eto Adojutofo: Awọn Ile iwosan yoo sọ fun oniduro ni kiakia iye owo ti wọn se akọsilẹ nipa lilo ẹrọ ayarabiaṣa nipasẹ Ṣíṣàlàyé awọn Anfani (Explanation of Benefits ,EOB) tabi gẹgẹ bi ẹni alàgàta to nsan owo ṣe dari.

2. Dídíyelé Awọn Alaisan Ti Wọn Ko Ni Eto Adojutofo: Ile iwosan yoo ṣe eto idiyele itọju alaisanfun oniduro lai fi akoko sofo. Owo ti oniduro njẹ yoo di mimọ nipa lilo isiro Gbogbo Owo To Wa Fun Sisan fun Eyikeyi Itọju (Amounts Generally Billed ,AGB). Isiro ti BSHSI ṣe ni isalẹ yi ṣe afihan ida-ninu-ọgorun (percentage) ẹdinwo ti o wa fun agbegbe kọọkan

   AGB:

   - Bon Scours Richmond: Ẹdinwo Ida marun-dịnlọgọrin ninu ọgọrun (75% ) ninu owo eto itọju awọn alaisan ti wọn da duro fun itọju nile iwosan ati Ẹdinwo Ida marun-dịnlọgọrin ninu ọgọrun (75% ) ninu owo eto itoju awọn alaisan ti wọn ko da duro ni ile iwosan.
   - Bon Secours Rappahannock: Ẹdinwo Ida marun-dịnlaadọrin ninu ọgọrun (65%) ninu owo eto itọju awọn alaisan ti wọn da duro fun itọju nile iwosan ati Ẹdinwo Ida marun-dịnlaadọrin ninu ọgọrun (65% ) ninu owo eto itoju awọn alaisan ti wọn ko da duro ni ile iwosan.
   - Bon Secours Kentucky: Ẹdinwo Ida marun-dịnlọgọrin ninu ọgọrun (75% ) ninu owo eto itọju awọn alaisan ti wọn da duro fun itọju nile iwosan ati Ẹdinwo Ida

marun-dịnlogọrin ninu ọgọrun (75% ) ninu owo eto itoju awọn alaisan ti wọn ko da duro ni ile iwosan.

- Bon Secours South Carolina: Ẹdinwo Ida ọgorin ninu ọgọrun (80% ) ninu owo eto itọju awọn alaisan ti wọn da duro fun itọju nile iwosan (ati Ẹdinwo Ida ogọrin ninu ọgọrun (80% ) ninu owo eto itoju awọn alaisan ti wọn ko da duro ni ile iwosan.

Eto Gbigba Owo Wọle

1. Awọn Ọna Gbogbogbogboo Fun Gbigba Wọlé (General Collection Practices): Pelu ilana yi, BSHSI lee lo gbogbo ona to tọ lati gba owo lọwọ awọn oniduro. Awọn ọna naa le jẹ fifi iwe/ lẹta sọwọ si oniduro, pipe ẹrọ ibanisọrọ, ati gbigbe iṣẹ owọ gbigba fun awọn ile iṣẹ alabaṣiṣẹpọ wọnyi, sugbọn ti ko mọ ni awọn wọnyi: Awọn to ngba owo asan silẹ (pre-collect), awọn to ngba owo ko to di pe akanti di gbese to soro lati san (early out vendors) ati awọn to ngbowo gbese to ti ṣòro ó san(bad debt vendors). BSHSI ko ni ta gbese alaisan kankan fun ile iṣe miran.

2. Gbigba Owo Ni Ọna To Le Awọn Igbesẹ To Le : BSHSI ati awọn ile iṣe abanigbowo le lo ECA nipa fifi ẹjọ onigbese sun ile iṣe to nse akọsilẹ awọn onigbese (credit bureau). Fifi ẹjọ oniduro sun ilẹ iṣẹ to nṣe akọṣịle awọn onigbese fun gbese to njẹ ko ni waye titi di ọgọta ọjọ lẹyin igba ti akoko eto idiyele ti pari. Yoo di mimọ fun oniduro ni ọgbọn ọjọ saaju akoko ti ile iṣẹ abanigbowo ti wọn jẹ alabasiṣẹpọ wa yoo gbe ẹjọ rẹ lọ si ọdọ ile iṣe to nṣe akọsilẹ awọn onigbese, wọn yoo si jẹ ko mọ iru awọn igbeṣẹ ECA ti wọn yoo gbe ti ko ba san owo naa, wọn yoo si fun u ni ẹ̀dà eto owo iranwọ fun alaisan ni ṣoki. Ko si eyikeyi ninu BSHSI tabi awọn ile iṣẹ abanigbowo ti wọn jọ jẹ alajọṣiṣepọ to le lo ECA kankan fun awọn oniduro ti wọn o ba tii gbiyanju lati mọ boya oniduro lẹtọ si iranlọwọ owo.

3. Ko Si ECA Lasiko Ti Wọn Ba Nseto Ibeere Fun Iranwọ Owo : BSHSI ati awọn alajoṣiṣẹpọ ti wọn jẹ ile iṣẹ Abanigbowo ko le lo ECA fun oniduro to ti kọwe beere fun iranwọ owo. Ti o ba di mimọ pe oniduro lẹtọ lati gba iranwọ owo, ti oniduro si ti san owo, BSHSI yoo da owo ti wọn gba lọwọ oniduro ni akoko to lẹto si iranwo owo pada to ba ti ju dọla marun ( $5.00) lọ. To ba ṣe pe owo iranwọ diẹ ni oniduro ri gba, BSHSI yoo da owo to ba ju owo to yẹ ki oniduro san lọ pada fun. BSHSI ko ni da owo to ba din ni dọla marun ($5.00) pada. Ti olubeere kan (an applicant) ba lẹtọ si owo iranwọ, eto ECA ko le bẹrẹ titi di ọgbọn ọjọ lati ọjọ ti wọn fi ontẹ lu owo iranwọ diẹ ti wọn fun.

4. Awọn Ona Owo Sisan (Payment Plans):

   a. Awọn Alaisan To Letọ Si Eto (Eligible Patients): BSHSI ati eyikeyi ninu awọn ile iṣẹ abanigbowo to nṣiṣẹ fun BSHSI yoo fun awọn oniduro ni anfani lati yan ọna ti wọn yoo fi san owo ti o jẹ, ki wọn si jọ ṣe adehun. Adehun ọna ati san owo naa yoo fi aye gba oniduro lati san owo ti o jẹ diẹdiẹ fun awọn asiko kan.

   b. Ilana to wa fun ona owo sisan :
   - Gbogbo ilana owo sisan ko ni owo ele ninu.
   - BSHSI ati oniduro yoo fi imọ sọkan lori gbogbo iye owo to yẹ lati maa san losoosu.
   - Gbese to wa ninu akanti naa gbọdọ di sisan láàárín akoko ti wọn ṣe adehun le lori.
   - Owo sisan gbọdọ waye ni gbogbo ọjọ karundinlogun osoosu.
   - Ni ilu New York: Owo osoosu ko gbọdọ ju idamẹwa ninu ọgọrun gbogbo owo oṣu (10% gross monthly income) lọ.

c. Eto Kikede Pe Ọna Owo Sisan Ti Fori Sańpán Ona owo sisan lee fori sanpan nigba ti oniduro ba kọ lati san awon owo leralera. Ti eleyi ba ṣẹlẹ, oniduro naa yoo gba iwe ìforísánpán, wọn yoo fi iwe yi ranṣẹ si adirẹsi oniduro ti wọn mọ gbehin. Lẹyin igba ti won ba ti sọ pe ona owo sisan ti forisanpan, BSHSI tabi ile iṣẹ abanigbowo le bẹrẹ lati lo gbogbo awọn ona lati gba owo naa pada lọna ti o ba eto yi mu.

5. Awọn Ile Iṣẹ Abanigbowo : Ile iṣẹ BSHSI lee fi akanti oniduro sọwọ si ile iṣẹ abanigbowo, ti o ba tẹle awọn ilana wọnyi:

A. Ile iṣẹ abanigbowo naa gbọdọ ni adehun ti a kọ silẹ pẹlu ile iṣẹ BSHSI.

B. Adehun ti a kọ silẹ laarin BSHSI ati ile iṣẹ abanigbowo gbọdọ fihan pe ṣiṣe ojuṣe ile iṣẹ abanigbowọ naa gbodọ wa ni ibamu pẹlu idawọle, àfojúsùn, awọn iwa to ṣe koko fun ile iṣẹ BSHSI, ati wọn ilana to wa pẹlu eto owo iranwọ ati eto idiyele ati eto gbigba owo.

C. Ile iṣẹ abanigbowo naa gbọdo gba lati fun oniduro ni ọgbọn ọjọ ki o to di pe yoo bẹrẹ ECA kankan. Gbedeke yi yoo wa pẹlu ẹda iwe ti o da lori koko eto owo iranlọwọ

D. Gbese naa yoo jẹ ti BSHSI siwaju si (eyi tumọ si pe, wọn o "ta" gbese naa fun ile iṣẹ abanigbowo)

E. Ile iṣẹ abanigbowo naa gbọdọ ni eto ti won nfi nmọ awọn oniduro to lẹtọ fun owo iranwọ. Ile iṣẹ abanigbowo naa gbọdọ sọ fun awọn oniduro ti eto owo iranlọwọ ba wa ki wọn si ran awọn oniduro ti wọn nilo owo iranlọwọ si ẹka to ntọju awon onibara ni ile iṣẹ BSHSI (Lábẹ́lé) 804-342-1500, (Laisan owo) 1-877-342-1500 tabi lori ikanni ayelujara wa : www.fa.bonsecours.org . Fun Ile iwosan Gbogbogboo Rappahannock, awọn oniduro lee pe nọmba804-435-8529 tààràtà.
Ile iṣẹ abanigbowo ko gbọdọ bere owo lọwọ oniduro to ti kọwe fun iranwọ owo.

F. O kere tan, ọgọfa ọjọ gbọdọ kọja lati ọjọ ti BSHSI ti fi iwe akọkọ sowọ si oniduro nipa akanti gbese to njẹ.

G. Oniduro ko maa duna-dura nipa ọna to fi maa san gbese to jẹ.